# AWỌN ASỌTẸLẸ ISAIAH NIPA KRISTI
# ATI IMUṢẸ WỌN

**Isaiah 7:14; 9:1-7; 11:1-5; 42:1-4; 53:1-12**

**ẸKỌ 364 --- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Nitori a bi ọmọ kan fun wa, a fi ọmọkunrin kan fun wa" (Isaiah 9:6).**

## Messia ti a Ṣeleri

Nigba ti a bi Jesu ni Bẹtlẹhẹmu, ọ̀pọlọpọ ileri Ọlorun ni a muṣẹ. Lati igba ọkunrin akọkọ ati obinrin akọkọ, ni ileri Olugbala ti wà. Lẹyin ti Adamu ati Efa dẹṣẹ, Oluwa sọ fun ejo pe: "Emi o si fi ọta sãrin iwọ ati obirin na, ati sãrin irú-ọmọ rẹ ati irú-ọmọ rẹ̀: on o fọ́ ọ li ori, iwọ o si pa ni gigĩsẹ" (Gẹnẹsisi 3:15).

Eyi ni ileri kin-in-ni nipa Messia (Ẹni Ami-ororo), Olugbala ti yoo gba awọn eniyan là kuro ninu ẹ̀ṣẹ wọn (Matteu 1:21).

Lẹyin eyi, Ọlọrun ṣe ileri kan fun Abrahamu: "Ninu rẹ li a o ti bukun fun gbogbo idile aiye" (Gẹnẹsisi 12:3), eyi ti a muṣẹ ninu Jesu Kristi. Bi ọdún ti n gori ọdún a n mú majẹmu Ọlọrun pẹlu Abrahamu wá si iranti awọn Ju. Awọn wolii n sọ fun wọn leralera nipa Messia wọn ti n bọ̀wá. Isaiah sọ asọtẹlẹ pupọ nipa wiwa Kristi ju eyikeyi ninu awọn wolii lọ.

## Wolii Kan

Isaiah jẹ́ wolii Juda. O fẹrẹ jẹ́ pe akoko kan naa ti Amọsi ati Hosea n waasu ni Isaiah pẹlu n waasu. O jẹ́ oloootọ wolii Oluwa lati igba Ussiah titi di ọjọ Hẹsekiah (Isaiah 1:1). Itàn sọ fun wa pe ikú ajẹriku ni Isaiah kú nitori awọn ohun ti o waasu nipa Ọlọrun.

Lati sọtẹlẹ ni lati sọ ohun ti n bọwa ṣẹ lọjọ iwaju ṣiwaju akoko rẹ̀ tabi lati waasu. Ọlọrun n fi awọn ohun ti n bọwa ṣẹlẹ lọjọ iwaju han awọn wolii Rẹ̀, o si misi wọn lati sọ ati lati kọ akọsilẹ awọn ohun wọnni ti Ọlọrun yoo muṣẹ. Ninu Bibeli a kà nipa awọn asọtẹlẹ ati akoko ti ọ̀pọlọpọ ninu wọn yoo ṣẹlẹ.

## Ibi Kristi

Ẹ jẹ ki a ṣe ayẹwo diẹ ninu awọn asọtẹlẹ Isaiah nipa Kristi. Isaiah kọ akọsilẹ ọ̀rọ Oluwa: "Nitorina, Oluwa tikalarẹ yio fun nyin li àmi kan. Kiyesi i, Wundia kan yio loyun, yio si bi ọmọkunrin kan, yio si pe orukọ rẹ̀ ni Immanuẹli." Eyi ni yoo jẹ́ àmi pe ọmọ naa ni Messia ti a ti ṣeleri. Fun eyi lati ṣẹlẹ yoo jẹ́ iṣẹ-iyanu nitoripe yoo jẹ́ ohun abami. Jesu jẹ́ Ọmọ Ọlọrun a si nilati nireti pé ki ibi Rẹ̀ jẹ́ iyanu ati iṣẹ-àrà, ki o si yatọ lọna kan si ibi ti ọmọ miiran. Njẹ asọtẹlẹ irú eleyi le ṣẹ? Bẹẹni o ṣẹlẹ. Nipa ibi Jesu a kà a pe angẹli kan sọ fun Maria, wundia, pe oun yoo jẹ́ iya ọmọkunrin kan ẹni ti oun yoo pè ni "JESU" (Luku 1:27, 31).

Nigba ti akoko tó, Maria bi Jesu (Matteu 2:1, 11). "Gbogbo eyi si ṣẹ, ki eyi ti a ti sọ lati ọdọ Oluwa wá li ẹnu woli ki o le ṣẹ" (Matteu 1:22).

Nitori pe ibi Jesu yii jẹ iṣẹ iyanu ti kò ye awọn eniyan, wọn kò fẹ gba a gbọ́. Ṣugbọn Bibeli jẹ́ otitọ, awọn ti o fẹ Oluwa gba ohun ti o sọ gbọ́. Jesu jẹ́ Ọmọ Ọlọrun, Oun nikan si ni Ẹni ti o le mú asọtẹlẹ yii ṣẹ. Jesu ki i ṣe eniyan lásán. Ọmọ Ọlọrun ni Oun iṣe.

## Awọn Orukọ Rẹ̀

Jesu jẹ́ Ẹni iyanu tobẹẹ ti a fi n pè E ni ọ̀pọlọpọ orukọ, Wolii ni ti sọ pe orukọ Rẹ̀ yoo jẹ́ Immanuẹli, itumọ eyi ti i ṣe "Ọlọrun wà pẹlu wa." Angẹli naa wi pe, "Jesu ni iwọ o pè orukọ rẹ̀: nitori on ni yio gbà awọn enia rẹ̀ là kuro ninu ẹ̀ṣẹ wọn" (Matteu 1:21). Jesu tún ni awọn orukọ miiran pẹlu. Wolii Isaiah wi pe: "A o si ma pe orukọ rẹ̀ ni Iyanu, Oludamọ̀ran, Ọlọrun Alagbara, Baba Aiyeraiye, Ọmọ-Alade Alafia." Lode oni a maa n saba tọka si Jesu pẹlu ọ̀kan ninu awọn orukọ wọnyii ninu orin ati iwaasu. Orukọ kanṣoṣo kò le ṣapejuwe Jesu. Yoo gba lilo pupọ ninu wọn lati sọ nipa titobi Rẹ̀. Jesu paapaa tilẹ fikun awọn orukọ wọnyii. O wi pe: "Emi ni oluṣọ-agutan rere" (Johannu 10:11); "Emi li ọ̀na, ati otitọ, ati iye" (Johannu 14:6); ati "Emi ni ilẹkun" (Johannu 10:9). Boya iwọ naa le fikún akọsilẹ ti a kà silẹ nihin. Ẹnikan ti ka orukọ ti o le ni ọgọrun-un ninu Bibeli ti a fi n pe Jesu.

## Ijọba Rẹ̀

Isaiah sọ asọtẹlẹ nipa Ijọba Jesu ati akoso ijọba Rẹ̀. Lonii ninu ọkàn wa Oun ni iṣe Ọba ati Alaṣẹ ayé wa. Ọjọ naa n bọ̀ ti Jesu yoo gba ipo Rẹ̀ gẹgẹ bi Alaṣẹ lori ohun gbogbo, "ỌBA AWỌN ỌBA, ATI

OLUWA AWỌN OLUWA" (Ifihan 19:16). Ijọba Kristi ki yoo nipẹkun. Oun yoo jọba titi lai (Heberu 1:8; Ifihan 11:15).

Ijọba Rẹ̀ jẹ́ ijọba alaafia ati ododo. Wolii Jeremiah sọ̀rọ nipa ijọba Kristi pẹlu. Jeremiah wi pe: "Yio si jẹ Ọba, yio si ṣe rere, yio si ṣe idajọ ati ododo ni ilẹ na" (Jeremiah 23:5).

Ijọba Kristi yoo yatọ si ti eniyan. "Yio mu idajọ wá si otitọ. Ãrẹ̀ ki yio mú u, a ki yio si daiyà fò o, titi yio fi gbé idajọ kalẹ li aiye" (Isaiah 42:3, 4). Oun ki yoo ṣe idajọ gẹgẹ bi iri ojú, tabi gẹgẹ bi nnkan ti dabi ẹni pe ó rí, ṣugbọn ijọba Rẹ̀ yoo jẹ́ ti otitọ ati ododo. "On ki yio si dajọ nipa iri oju rẹ̀, bẽni ki yio dajọ nipa gbigbọ́ eti rẹ̀; ṣugbọn yio fi ododo ṣe idajọ talakà, yio si fi otitọ ṣe idajọ fun awọn ọlọkàn tùtu aiye" (Isaiah 11:3, 4). Idajọ Rẹ̀ yoo jẹ́ ododo nitori pe "ẹmi Oluwa yio si bà le e," yoo si fun Un ni "ẹmi ọgbọ́n ati oye, ẹmi igbimọ̀ ati agbara, ẹmi imọran ati ibẹ̀ru Oluwa."

**Aanu**

A sọ asọtẹlẹ nipa Jesu pe Oun yoo jẹ alaanu. "Iyè fifọ́ ni on ki yio ṣẹ." Nigba ti Jesu wà ni ayé, O fi aanu hàn fun awọn ti o wà ninu irora. O wo ọ̀pọlọpọ ti wọn n ṣaisan sàn. O si fi itunu ati iranwọ fun awọn ti o wá A. Lode oni nigba ti awọn ti a di ẹru wiwo le lori ti wọn si n jiya ba ké pè E ninu adura, O n tú wọn silẹ. Onipsalmu wi pe: "Oluwa mbẹ leti ọdọ awọn ti iṣe onirobinujẹ ọkàn; o si gbà iru awọn ti iṣe onirora ọkàn là" (Orin Dafidi 34:18).

**Ijiya Rẹ̀**

Isaiah pẹlu sọtẹlẹ nipa ijiya Olugbala. Ọpọlọpọ ọdún ṣiwaju kikan Kristi mọ́ agbelebu, Isaiah sọ awọn ọ̀rọ wọnyii bi ẹni pe o ti ṣẹlẹ: "A ṣá a li ọgbẹ nitori irekọja wa, a pa a li ara nitori aiṣedede wa; ina alafia wa wà lara rẹ̀, ati nipa ina rẹ̀ li a fi mu wa lara da." Nitootọ Jesu ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ lati pa ẹ̀ṣẹ awọn ti o ba ronupiwada ti wọn si gbagbọ́ rẹ́. Jesu ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ ki awọn eniyan ba le ri iwosan fun aisàn ati arùn wọn. Nigba miiran igbesi-ayé Jesu kò fi bẹẹ báradé. A korira Rẹ̀ a si gan An. "Awọn Farisi, ti nwọn ni ojukokoro si gbọ́ gbogbo nkan wọnyi, nwọn si yọ-ṣùti si i" (Luku 16:14). "Awọn ọlọ̀tọ ilu rẹ̀ korira rẹ̀, nwọn si rán ikọ̀ tẹ̀le e wipe, Awa kò fẹ ki ọkunrin yi jọba lori wa" (Luku 19:14). Jesu sọ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pe: "Bi aiye ba korira nyin, ẹ mọ̀ pe, o ti korira mi ṣaju nyin" (Johannu 15:18).

**Fun Wa**

A sọ fun Jesu pe ki O fi ilẹ awọn ara Gadara silẹ (Marku 5:17). Wọn hùwa abùkù si I "ẹni-ikãnu, ti o si mọ̀ ibanujẹ." Gbogbo nnkan wọnyii ni Kristi faradà ki awa ba le ni igbala ati iyè ainipẹkun. O jiya fun ẹ̀ṣẹ wa –"olõtọ fun awọn alaiṣõtọ" (1 Peteru 3:18).

"A jẹ ẹ ni iyà, a si pọ́n ọ loju, ṣugbọn on kò yà ẹnu rẹ̀." Jesu kò wijọ́ bẹẹni kò si kùn wi pe Oun n jiya fun awọn ẹlomiran. Awọn ẹlomiran a maa fẹ́ pe ki a bá wọn kẹ́dùn, wọn a si maa wijọ́ nigba ti o jẹ pe awọn tikarawọn ni o fa ijiya ati itiju wá sori ara wọn. Jesu, Ẹni ti kò mọ ẹ̀ṣẹ ri ni a sọ di ẹ̀ṣẹ fun wa. A sun Jesu lẹsun eke wọn si gbo O lẹjọ, ṣugbọn Oun kò tilẹ dá ati da ara Rẹ̀ lare; ọ̀pọlọpọ igba ni kò tilẹ dahun ọ̀rọ kan (Matteu 26:63; 27:14; Luku 23:9).

Jesu tikara Rẹ̀ ni O yọọda ara Rẹ̀ fun awọn ẹlomiran. Gbogbo ẹ̀ṣẹ wa ni a di le E lori. O jiya fun wa. Ṣugbọn ki ni awa ṣe fun Un? Ni akoko ajọyọ̀ Keresimesi yii, nigba ti a n fi ẹ̀bun fun awọn ẹlomiran, a ha n fi ayé wa ati iyin wa fun Un bi ẹ̀bun? Ọlọrun fun wa ni ẹ̀bun ti o tobi ju lọ nigba ti O fi Ọmọ Rẹ̀ fun wa. Lati ọdọ Rẹ̀ ni iwọ ti lè ni iye-ainipẹkun. O lè ri igbala. Njẹ o ni i lonii? Iwọ pẹlu le ni i, nipa gbigbadura, jijẹwọ́ ẹ̀ṣẹ rẹ, nipa kikọ ẹ̀ṣẹ rẹ̀ silẹ, ati nipa gbigba awọn ileri Rẹ̀ gbọ́.

**Ikú Jesu**

Awọn asọtẹlẹ miiran wà ti Isaiah sọ ti a mu ṣẹ nigba ikú Jesu. "A ti ke e kuro ni ilẹ alãye: nitori irekọja awọn enia mi li a ṣe lù u." Iku Rẹ̀ wà "pẹlu awọn enia buburu" – laaarin awọn ole meji (Matteu 27:38) – ati "pẹlu ọlọ̀rọ̀" – ninu iboji Josẹfu (Matteu 27:59, 60).

Jesu Kristi, Ọmọ Ọlọrun, mú asọtẹlẹ ṣẹ nigba ti a bi I ni Bẹtlẹhẹmu ti Judea. O mu asọtẹlẹ ṣẹ nigba ti O fi Ẹmi Rẹ̀ lelẹ̀ ti o si "rù ẹ̀ṣẹ ọ̀pọlọpọ." Nisisiyii paapaa, Kristi n mú asọtẹlẹ ṣẹ sibẹ nitori pe O wà ni ọwọ ọtun Ọlọrun, O si n bẹbẹ̀ fun wa (Romu 8:34). "Nitorina o si le gba wọn là pẹlu titi de opin, ẹniti o ba tọ̀ Ọlọrun wá nipasẹ rẹ̀, nitoriti o mbẹ lãye titi lai lati mã bẹ̀bẹ̀ fun wọn" (Heberu 7:25).

Isaiah jẹ́ eniyan Ọlọrun, ẹni ti o sunmọ Ọlọrun timọtimọ ti o si ṣiṣẹ fun Ọlọrun. O ni anfaani nlánlà lati sọtẹlẹ nipa Kristi, Ọmọ Ọlọrun. A ti kà á ninu Bibeli pé ọ̀pọlọpọ ninu asọtẹle wọnyii ni a ti muṣẹ. Awọn iyoku yoo si ṣẹ bakan naa gẹgẹ bi a ti mú awọn miiran ṣẹ. Ẹ jẹ ki a fi adura ati igbọran pese ara wa silẹ fun Ijọba Kristi ki a ba le wà pẹlu Rẹ̀ nibẹ. Ẹ jẹ ki a ṣe bẹẹ lonii nipa sisin Ọmọ-ọwọ Bẹtlẹhẹmu naa.

## AWỌN IBEERE

1 Ta ni a n pè ni wolii?
2 Darukọ diẹ ninu awọn wolii.
3 Ewo ni o sọ pupọ nipa Kristi?
4 Ki ni ṣe ti ibi Jesu jẹ́ iṣẹ àrà ati iṣẹ-iyanu?
5 Ki ni orukọ iya Jesu?
6 Ki ni ṣe ti Jesu jiya ti O si kú?
7 Asọtẹlẹ Isaiah wo ni a muṣẹ nigba ikú Jesu?
8 Ewo ninu awọn asọtẹlẹ Isaiah nipa Kristi ni a kò iti muṣẹ?